# JOSẸFU, OLUTUMỌ ÀLÁ

**Gẹnẹsisi 40:1-23; 41:1-36**

**ẸKỌ 35 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: “Bi o ba kù ọgbọn fun ẹnikẹni, ki o bère lọwọ Ọlọrun” (Jakọbu 1:5).**

**Ninu Tubu Sibẹ**

Awọn ọba igba aye Josẹfu dabi awọn adanikan-paṣẹ ti a ti n gbọ nipa wọn ni awọn ilu alawọ funfun ni ọdun diẹ sẹyin. Bi ẹnikẹni ba ṣẹ̀ wọn, a o fi sinu tubu lai wadii ọ̀ran rẹ̀, boya a si le gbagbe rẹ̀ fun ọdun pupọ.

Bayii ni Josẹfu bá ara rẹ ninu tubu – ki i ṣe nitori ohun buburu kan ti o ti ṣe, bi ko ṣe pe a kò jẹ ki obinrin kan mu ifẹ inu rẹ ṣẹ, o si fẹ gbẹsan. Lai pẹ, a fi awọn ọkunrin meji kan ti wọn ti ni ipo giga ninu aafin sinu tubu pẹlu rẹ nitori wọn ti ṣe nnkan kan ti inu ọba Farao kò dun si. Awọn ọba buburu wọnni maa n bẹru nigbakuugba pe ẹni kan n fẹ gbe ohun oloro fun wọn jẹ, tabi ki o pa wọn ni ọna miiran ẹ̀wẹ̀: boya idi rẹ̀ niyii ti a fi fura si awọn ọkunrin wọnyii. Iṣẹ olori agbọti ọba ni lati gbe ọti fun ọba ti o wa lori itẹ; bẹẹ ni o si jẹ iṣẹ alase lati boju to ounjẹ ati akara ọba.

Nitori oju-rere ti Ọlọrun ti fun Josẹfu lọdọ awọn onitubu a fi ṣe alabojuto awọn onde titun yii. Ni owurọ ọjọ kan nigba ti o tọ̀ wọn lọ, boya o gbe ounjẹ aarọ wá fun wọn, wọn fajuro. Josẹfu jẹ oninuure, o si n fẹ mọ idi rẹ̀ ti inu wọn fi bajẹ. Wọn ró ala ti wọn lá fun un.

Awọn ara Egipti ni ọpọlọpọ awọn amoye ati awọn alalupayida, awọn ti wọn n sọ ohun ti yoo ṣẹlẹ nipa irawọ. Ki i ṣe ohun ajeji fun awọn eniyan lati ró ala wọn fun iru eniyan bayii, ki wọn si gbọ itumọ ala wọn: ṣugbọn ninu tubu nihin, ko si ẹni ti yoo sọ itumọ ala naa fun wọn. Josẹfu jẹ ki o di mimọ̀ fun wọn pe ko tọ́ ki wọn wá awọn aworawọ tabi awọn alasọtẹlẹ, nitori Ọlọrun nikan ṣoṣo ni O le fun ala ni itumọ tootọ.

Josẹfu ti wà ni Egipti fun nnkan bi ọdun mọkanla nisisiyii ṣugbọn lai ka ohun ti o yi i ká si, o ti gbe igbesi-aye rẹ ni ọna ti o fi ni igbẹkẹle sibẹ pe Ọlọrun yoo gbọ́ ti oun nigba ti oun ba gbadura. Kò wi pe: “Boya n ko tun ni pada si ile mọ nitori bẹẹ ki ni o jamọ bi mo ba ṣe ohun ti o wù mi? Ko si ọ̀kan ninu awọn ọrẹ mi ti yoo mọ bi mo ba dẹṣẹ kekere kan: yoo si rọrun lati maa ba awọn eniyan wọnyii gbe bi mo ba n sin oriṣa wọn.” O gbe igbesi-aye rẹ lati wu Ọlọrun lojoojumọ, o ranti pe Ọlọrun n ri ohun gbogbo ti a n ṣe, yoo si fun wa lere gẹgẹ bi iṣẹ wa.

**A Tumọ Ala**

Nigba ti a n fẹ idahun lati ọdọ Ọlọrun, inu Josẹfu dun ni tootọ pe oun wa ni ipo ti adura oun le ṣe itẹwọgba lọdọ Ọlọrun. Nigba ti o sọ fun awọn ẹlẹwọn naa pe ti Ọlọrun ni itumọ i ṣe, o le fi kun un pẹlu igboya pe, “Emi bẹ̀ nyin, ẹ ró wọn (awọn àlá naa) fun mi.” O sunmọ Oluwa to bẹẹ gẹ ti o ni iṣọkan pẹlu Rẹ̀, gẹgẹ bi Ọrọ Ọlọrun ti sọ nipa awọn ti a sọ di mimọ́ pe: “Nitori ati ẹniti nsọni di mimọ́ ati awọn ti a nsọ di mimọ́, lati ọdọ ẹnikanṣoṣo ni gbogbo wọn: nitori eyiti ko ṣe tiju lati pè wọn ni arakunrin” (Heberu 2:11).

Agbọti ọba ni o kọ sọ ala rẹ, inu rẹ si dun lati gbọ bi Josẹfu ti wi pe eyi n sọ asọtẹlẹ idasilẹ rẹ titi ọjọ mẹta. Gẹgẹ bi Josẹfu kò ti lẹtọọ lati wà ninu tubu o ya a lẹnu pe wọn ti gbagbe oun, o sọ fun agbọti ọba naa lati ranti oun nigba ti a ba da a silẹ. O yẹ ki agbọti ọba yii fi ọkàn imoore hàn fun Josẹfu lati ran an lọwọ ki o ba le jade. Ṣugbọn lẹsẹkẹsẹ ti a dá agbọti ọba yii silẹ, o gbagbe lati fi aanu hàn fun ẹlomiran ti o n jiya lai tọ. Ọlọrun n wo ọkan lile ti o wa lọkan ẹlẹṣẹ, wọn yoo si gba idajọ Rẹ̀ ni ọjọ kan. Jesu wi pe, “Niwọn bi ẹnyin kò ti ṣe e fun ọkan ninu awọn ti o kere julọ wọnyi ẹnyin kò ṣe e fun mi. Awọn wọnyi ni yio si kọja lọ sinu iya ainipẹkun: ṣugbọn awọn olõtọ si iye ainipẹkun” (Matteu 25:45, 46).

Nigba ti olori alase mọ pe itumọ ala kin-in-ni dara, oun paapaa sọ ala ti rẹ̀ fun Josẹfu. Ṣugbọn oun ko ṣe oriire to bẹẹ. O le jẹ pe oun ti ṣẹ ẹṣẹ kan ti o yẹ fun ijiya. A mu un jade kuro ninu tubu lẹyin ọjọ mẹta, a bẹ́ ẹ lori, a si fi kọ́ sori igi, gẹgẹ bi Josẹfu ti tumọ ala rẹ̀.

A gbagbe Josẹfu sinu tubu fun ọdun meji lẹyin naa. Eyi jẹ akoko ti o pẹ́ pupọ loju rẹ, o si ni lati dun un pupọ pe agbọti ọba yii ko tilẹ laanu rara. Ṣugbọn Ọlọrun ki i gbagbe awọn ti Rẹ̀ bi o tilẹ jẹ pe awọn nnkan ki i fi igba gbogbo wá sọna wa lẹsẹkẹsẹ ti a ro pe wọn ni lati wá, ranti pe Ọlọrun mọ eyi ti o dara ju lọ. Oun yoo si mu ohun gbogbo ṣẹ ni akoko ti Rẹ̀ ati fun ogo Rẹ̀. Oun kò fẹ ki a fajuro nigba ti ileri Rẹ̀ ba falẹ, ṣugbọn O ti wi pe, “Ẹ duro jẹ, ki ẹ si mọ̀ pe emi li Ọlọrun” (Orin Dafidi 46:10). Ati pe, “Nitori bi ọrun ti ga ju aiye lọ, bẹ̃ni ọ̀na mi ga ju ọ̀na nyin lọ, ati èro mi ju èro nyin lọ” (Isaiah 55:9). Bi a ba saa ti le kọ bi a ti i gbẹkẹle E patapata!

**Ala Ọba**

Lẹyin ọdun meji, ọba la ala meji ti o ro pe wọn ṣe pataki, o si pe gbogbo awọn amoye ati awọn alafọṣẹ ti o wa ni ijọba rẹ̀ lati sọ itumọ ala naa. Ṣugbọn Ọlọrun ni O fi ala naa han an, ko si le ye awọn iranṣẹ eṣu. O gba pe ki a ni ọgbọn ọrun ki a to le mọ itumọ awọn ohun ti i ṣe ti Ọlọrun.

Nigba naa ni agbọti ọba ranti ohun ti o yẹ ki o ti ṣe lati igba ti a ti da a silẹ kuro ninu tubu. O le dabi ẹni pe inu agbọti ọba yii dùn pupọ lati gba ipo rẹ atijọ pada to bẹẹ ti yoo fi maa ronu nipa rẹ lojoojumọ -- ṣugbọn kò ṣe bẹẹ. O sọ fun ọba pe Josẹfu tumọ ala ti oun ati olori alase ti lá daadaa, ati pe oun si gbagbọ́ pe ẹrú ọmọ Heberu naa le ran ọba lọwọ. Farao yara paṣẹ ki a mu Josẹfu wa siwaju oun, o si sọ ala ti o da a laamu naa fun Josẹfu. Josẹfu ko gba iyin kankan fun ara rẹ, fun ọgbọn ti o ni lati tumọ ala, ṣugbọn o fi gbogbo ogo naa fun Ọlọrun. A gbọdọ ranti nigbakuugba pe Ọlọrun ni Olufun ni ni gbogbo ẹbun rere ati ẹbun pipé: bi a ba si ṣe iṣẹ wa daradara, tabi a ni aṣeyori kan, a ko gbọdọ gberaga, ki a si ro pe a ti tó tán, ṣugbọn a gbọdọ dupẹ lọwọ Ọlọrun pe O fun wa ni awọn ẹbun wọnyii.

O dabi ẹni pe Josẹfu mọ pe Ọlọrun yoo bukun fun ọba naa nitori o wi pe, "Ọlọrun ni yio fi idahùn alafia fun Farao."

Igbẹkẹle awọn ara Egipti fun ounjẹ duro lori Odo Nile. Ojo diẹ ni o n rọ̀ nibẹ, ṣugbọn iṣẹ ọgbin ṣe e ṣe nipa fifa omi lati inu odo naa. Ni ọdọọdun ni o maa n kún bo bèbè rẹ, nipa bayii, o si maa n mu ki ilẹ lọra si i, o si maa n rin ilẹ fun igba diẹ. Ni iwọn ọdun diẹ sẹyin, a ti ṣe ọna lati maa sé omi odo naa mọ́ ati lati tọju omi naa de igba ọ̀dá; ṣugbọn ni igba laelae, bi omi naa ba kun ju, ti o si wa lori ilẹ fun ọjọ pipẹ to bẹẹ ti a ko le gbin ohun-ọgbin ni akoko rẹ, abayọri rẹ ni ìyàn. Bẹẹ gẹgẹ ni, bi omi ko ba kun tó, ohun-ọgbin ki yoo hù, ìyàn yoo si tun mu bakan naa. Bi awọn ara Egipti ti ri pe ẹmi wọn rọ mọ́ odo Nile yii, wọn n bọ ọ bi oriṣa.

Gẹgẹ bi a ti ri i nipa ala kin-in-ni ti Farao lá, boya wọn yoo ni ọdun ọpọ naa nigba ti odo yii ba kun daradara, bẹẹ ni ọdun iyan ti yoo tẹle e yoo wà pẹlu nipa iru ipo ti odo yii ba wa.

Ninu ala keji ni a tun ri ohun ti o ba ni lẹru, eyi ni afẹfẹ lati ila-oorun. Afẹfẹ yii n fẹ la aarin aṣálẹ̀ Arabia já, yoo si ti gbona pupọ ni akoko ti yoo de Egipti. Awọn arinrin-ajo wi pe lojiji ni afẹfẹ yii n de, gẹgẹ bi ikuuku ti o bolẹ; ati gẹgẹ bi ikilọ fun awọn eniyan ilẹ naa, wọn yoo yara doju bolẹ ki wọn baa le ri afẹfẹ ti o to lati mu wọn wa laaye. Pẹlu iru ikiyesara bẹẹ paapaa, arinrin-ajo kan sọ pe oun ti fa afẹfẹ gbigbona simu to bẹẹ ti oun ni lati gbe ibi ti o tutu fun oṣu pupọ ki oun to le sàn. Ohun-ọgbin eyikeyi ti o ba tilẹ ti hù bi o tilẹ ṣe pe ko si omi, ni afẹfẹ buburu yii n fẹ́ danu.

### Itumọ Ala Naa

Josẹfu sọ fun Farao pe, Ọlọrun n fi han an pe Oun yoo fun un ni ọdun meje ọpọ ounjẹ laaarin eyi ti ohun ọgbin yoo hù lọpọlọpọ; ṣugbọn ọdun meje iyàn ni yoo tẹle e. Ọdun meje ti kò ni si ohun ọgbin yoo mu ijiya pupọ wa sori ayé, ọpọlọpọ eniyan ni yoo si ku bi ko ṣe pe a ba ṣe eto silẹ ṣaaju akoko naa. Josẹfu gba ọba niyanju lati tọju ounjẹ ni akoko ọpọ lati fi bọ́ awọn eniyan nigba ti iyan ba de.

## AWỌN IBEERE

1 Njẹ Josẹfu sọ itumọ ala agbọti ọba ati alase ọba daradara?

2 Ki ni Josẹfu wi fun olori agbọti ọba pe ki o ṣe fun oun?

3 Njẹ Josẹfu gba iyin fun ara rẹ nitori o le sọ itumọ ala?

4 Ki ni ṣe ti Ọlọrun jẹ ki Farao lá ala meji ti o ni itumọ kan naa?

5 Njẹ o ro pe Ọlọrun ni idi kan ti O fi jẹ ki Josẹfu lọ si Egipti?